ADURA FUN ỌSẸ YI

Edumare Ọba Ogo jẹki ire ile aiye so oju wa kasi jẹ nibẹ pẹlu alafia ati ilera.

# IRAWỌ ★ OBOKUN

OWE ỌSẸ YI

Banusọ ma ba enia sọ, enia ko si mọ, aiye ti d'eke.

Vol 3 No. 133 ILESHA. MONDAY, APRIL 11 1955. IYE OWO: TORO


## WON TI DA MERIN SILE NINU AWON TI WON F'EJO IPANIA KAN L'OYO



ỌLỌLA ỌBAFEMI AWOLỌWỌ

On ni Oluṣeto fun eto iṣe Ijọba ni, asiko ti wọn ṣe eto Ijọba titun Eto na yio bere ni ile Ijeṣa ni ọjọ kejidinlogbọn oṣu yi.

### ARIYỌ ATI AWỌN AṢOJU IJEṢA IGBIMỌ

(Lati ọwọ Ọgb ni S. Akindele Ojo)

Mo ka ọrọ ilara ti Ọgbẹni kan ti wọn pe ni Donald Ade Ariyọ kọ si ọkan ninu awọn iwe irohin awọn ẹgbẹ Ọlọpẹ ni Ibadan ni ọjọ Kọkandinlogbọn oṣu to kọja.

Nigbati mo ranti pe iwe irohin na jẹ ọkan ninu awọn iwe irohin ti ko ni iteriba fun ihuwa bi ọmọluwabi, ti mo si mọ pe ẹniti o kọ iwe na gan jẹ ọkan ninu awọn oṣelu Ilẹ Ijẹṣa to ti nri bi ẹni nri sinu omi ti o si ni lati ma mu ofurufu tabi ojiji lati gba ara rẹ silẹ, mo ti toribẹ ronu si tẹlẹ pe nse lo yẹ ki a kasi nkan lasan.

Ṣugbọn nigbati mo ranti ọkan ninu awọn ẹkọ ti iwe mimọ kọni pe ki a "da aṣiwere lohun gẹgẹbi were rẹ ki o ma ba gbọn loju ara rẹ" ni mo fi pinu lati fesi diẹ.

AWỌN AJẸLẸ

Ọgbẹni Ade Ariyọ ti mo nsọrọ rẹ na sọ ọpọlọpọ isọkusọ si Ọlọla J O Fadahunsi nitoripe o taku ni igbimọ iṣofin ti Ẹkun Iwọ Orun pe ki igbimọ na ma se gba lati na (£17,160) ẹgbẹrun poun ọna mẹtadinlogun pẹlu ọgọjọ poun fun awọn oṣiṣẹ Ijọba mẹjọ, ipo iṣẹ awọn ti Ọlọla na sọpe ko wulo mọ.

O dun mọ mi pupọ wipe Irawọ Obokun ti ọsẹ to kọja gbe iba ọrọ na jade nipa bẹ gbogbo ẹnyin ọkawe Irawọ Obokun ni yio ti ni anfani lati ri ohun ti Ọ.ọla na wi gan ka.

Awọn ti on ba wi ni awọn Rẹsidẹnti to nṣiṣẹ ni Province ti ipinlẹ rẹ jẹ mẹta, to si kọ ọkan ninu rẹ ti patapapata ti o si nda idarudapọ ati aifọkanbalẹ silẹ ni ibomiran ninu Province na".

O pari ọrọ rẹ wipe "bẹni yio ma gba ẹgbẹwa poun lọdun" o wa fi kun pe "fifun iru awọn oṣiṣẹ be laye ni abẹ Ijọba jẹ ifowosofo".

Iyẹn ni Ariyọ pe ni "iṣo-

(Bẹrẹ ni oju iwe 2)



ỌLỌLA J. O. FADAHUNSI

On ni Ẹniti Ariyọ kọwe nipa rẹ ninu iwe irohin kan ni Ibadan.

Ọgbẹni S. Akindele fi eda (copy) idahun to kọ si awọn iwe irohin ti elede geri ranṣẹ si wa. O jade lọsẹ yi.

### KOTU LỌKỌLAYA TI BẸRẸ

(Lati Ọwọ Oloye S. O. Adedeji)

Eyi ni lati kede si gbogbo enia papa awọn lọkọlaya to lẹjọ ni kotu pe a ti si kotu na a si ti bẹrẹ iṣẹ ni bẹ lati ọjọ keji osu yi.

Nitorina ki olukuluku awọn enia ti wọn ba ni ẹjọ si kotu yi gba ikede yi gẹgẹbi ifilọ – (notice) – ki olukuluku si bẹrẹ lati ma wa si kotu Ibilẹ yi ati pe ki wọn si tete ma de ni agogo mẹjọ owurọ

Ki olukuluku ọkunrin ti yi o ba ma wa si kotu maṣe gbagbe lati mu iwe owo ori – tax Receipts – wọn lọwọ nigbati nwọn ba mbọ ni kotu.

### ẸGBẸ ỌLỌPẸ ATI OMI ẸRỌ ILEṢA

(Lati ọwọ Akọwe NCNC Ileṣa)

Gbogbo onigbagbọ lo mọ pe ki a to bi Jesu ni Jesu ti ni ọta. Ṣugbọn ẹniti o ba ka iwe mimọ jinlẹ yio ripẹ gbogbo awọn ọta Jesu lo fi ọwọ ara wọn ṣe ara wọn. Bẹ gẹgẹ ni ọrọ Ijọba to bọ sọwọ ẹgbẹ NCNC ni Ilẹ Ijẹṣa, eyiti wọn yio bẹrẹ iṣeto rẹ laipẹ.

A ti loyun ijọba na, ṣugbọn a ko i ti bi silẹ. Ṣugbọn sibẹṣibẹ awọn ẹgbẹ ọlọpẹ ti gọ de gẹgẹ bi ọta. Ẹru ti ki i ṣe tirẹ wọn ti ndi ru.

Fun akiyesi lati nkan bi oṣu mẹta sẹhin ni wọn ti fi ibosi bọ ẹnu pe Ẹgbẹ Alakukọ tifi ogun sile pẹkun owo'ri nitori ina alatunmọle. Ẹgbẹ Akukọ ṣe alaye nigbana, ọrọ na ku. Ṣugbọn ni aipẹ yi ni awọn ẹgbẹ onirọ yi bẹrẹ kundekunde ṣiṣe pe Ẹgbẹ Akukọ ti fi ọwo nla kun owori nitori owo omi ẹrọ.

Awa ẹgbẹ NCNC iba ti ṣe alaye lori ọrọ na, ṣugbọn ni-

(Bẹrẹ ni oju iwe 4)

### ALUFA RANSON KUTI KU NI ABẸOK TA

Ni ọsan ọjọ kẹta osu yi ni irohin tan kakiri Ilẹ Naijirie pe Alufa I. O Ransome Kuti di eni oruu,

Alufa na ni Baba Ẹgbẹ awọn Oluko jakejado Naijiria titi di oṣu kini ọdun yi Odidi nkan bi ọdun marundinladọta ni Ologbe na fi ṣe iṣẹ Oluko, o fi nkan bi ọgbọn ninu rẹ jẹ Alabojuto Grammar Schoo ti Abẹokuta.



ỌLỌLA OLU KỌMỌLAFẸ

Ninu eti ti Ọgbẹni Akindele Ojo nbi Ọgbẹni Ariyọ, o sọ pe yiyan si igbimọ isofin ti Ọlọla yi jẹ irora nla fun awọn enia bi Ariyọ.

### ẸJỌ IPANIA TI ỌYỌ T NPARI

Ejọ ipania to ṣelẹ nigba rogbodinyan to ṣelẹ ni Ọyọ ti bere.

Kotu gipa ti da Salawu Akande ati Salawu Alegun lọ fun silẹ ni ọjọ kini osu yi.

Awọn mejeji jẹ ọmọ Ẹgbẹ ti wọn npe ni Ọyọ Parapọ, ẹsun ti wọn fi kan won nipe wọn pa Ọgbẹni Raji Oluokun ninu rogbodiyan to ṣelẹ lọjọ karun oṣu September 1954.

Kotu tuu ti da awọn Ọgbẹni Lasisi Atanda ati Ponnọlọla Onikere silẹ ni ọjọ kẹta oṣu yi. Ẹsun ti wọn fi kan nipe wọn pa Ọgbẹni Ṣitu Fagbemisọla ni ọjọ rogbodiyan kan na ni Ọyọ.

Ni ọjọ karundogun oṣu yi wọn fi isajọ ti awọn mẹrin miran si.

### OLE GBE KỌKẸ LỌ

Ni ọfọ keji oṣu yi ni ole kan gbe kẹkẹ ti Ọgbẹni Olu George lọ ni iwaju ile rẹ ni B 54 Adugbo Okeṣa Ileṣa.

Nọmba to jẹ ami ara kẹkẹ na ni Fram No S 77735: Orukọ gẹgẹ na ni SUN Beam

Ọgbẹni na bẹ ẹnikẹni ti o ba ba ri kẹkẹ na ki o fi han Ọlọpa tabi ki o fi han ẹnikẹni ni B 54 Okesha St Ilesha


MA RA

**Irawo Obokun**

LỌSỌSẸ

## AFI IPILẸ ILE ISIN IJỌ APOSTELI LELẸ
(Lat ọwọ Evangelist)

Lọjọ Monday ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu kẹta ọdun yi ni a fi ipi lẹ il isin Aposteli lelẹ ni adugbo Ikoyi. The Apostolic Church Ikoyi.

A bẹrẹ isin na ni ago mẹje koja iṣẹju mẹdogun. Alufa ti o fi orin bẹrẹ isin na ni J. O. Fọwẹ. (Orin 304) lẹhin na ni Pastor Ọlakanpọ ka Ps. 8 lẹhinna pastor P. O. Fasan gbadura si okuta ti a kọjọ fun ipilẹ ile na, o si ka ilana eto isin na lati inu Samo Kiyesi mo ti pataki okuta igun ile asayan iyebiye lelẹ ni Sioni___ Lẹhin na o ti ipinlẹ ile na lelẹ loruko Baba ati ni ti ọmọ, ati ni ti Ẹmi mimọ, gbogbo enia si se amin.

O si tun paṣẹ pe ki awọn Alufa mẹta toku tun lọ se bẹ gẹgẹ ni igun ile mẹta toku.

Lẹhinna lo tun ka ọrọ Ọlọrun Esra 3—10. Nigbati awọn ọmọle si fi ipinlẹ Tempili Oluwa lelẹ nwọn mu awọn alufa duro ninu aṣọ wọn, nwọn mu ipe lọwọ, ati awọn ọmọ Lefi, awọn ọmọ Asafu mu Kiribali lọwọ lati ma yin Oluwa gẹgẹ bi ilana Dafidi Ọba Israeli.

Lẹhinna lo fi ọrọ diẹ gba awọn enia niyanju fun iṣẹ rere ti nwọn dawọle.

Lẹhin ọrọ iyanju, o fi aṣẹ fun ẹni meji pe ki wọn gba dura. Ẹni kini ti o gbadura ni ọgbẹni T. Fajuyigbe. Ẹni keji ni Pastor Adefidipẹ.

Lẹhin adura ni Pastor Fowẹ tun fi orin 129 pari isin na, o siṣe ifilọ pe, ki gbogbo awọn ti o ti mura silẹ fun iribọmi (Baptism) ki o ma mṣo ni eti odo nigbati a ba pari isin. Igbati a kọrin na tan Pastor. Fasan ṣe ore-ọfẹ, gbogbo enia si ke ogo si Oluwa Lẹhinna ni awọn enia si fi ayọ mu ọrẹ wa fun iṣẹ ile na.

Awọn enia pataki ti o wa sibi isin na ni Pastor P. O Fasan, G. E. S. Ọlakanpọ J. A. Ibidapọ, J. A Fowẹ, J.A. Adefidipẹ, Evangelists. G. O. Ọshọbu, G. O. Obembe, S. J. O. Oluwafẹmi, Awọn alagba J O Apoẹṣọ, S O Bewaji, J Fa ṣugba, Alagba pataki wa lati Oke-Oye. A si pari isin na ni ago mẹjọ ku ogun iṣẹju. Fun ogo Oluwa ni ile na yio jẹ.



ỌGBẸNI D. ỌLA. ỌṢUNLOYE

On na jẹ ọkan ninu awọn Olukọ ile iwe to ti nṣe Kanṣẹlọ to tan ti de Kanṣẹlọ. Ọgbẹni S. Akindele Ojo sọpe Donald Ade. Ariyọ t' kọwe ọbẹ nipa awọn Olukọ bẹ.



ỌGBẸNI MICHAEL ADEBAYỌ ẸṢỌ

On na jẹ ọkan ninu awọn to ti wọle si igbimọ ijọba ti apapọ ipinlẹ Ijẹṣa. Fun aṣeyẹ ṣiṣi igbimọ na laipẹ awọn ẹgbẹ NCNC glo ṣe isin idupẹ ni Ilọrọ ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi.

## ARIYỌ ATI AWỌN AṢOJU IJẸṢA
Bẹrẹ Lati oju iwe 1

fintoto lọna odi nigbati o sọ pe "iwe ti Ijẹṣa fi ki Gomina kabọ fihan pe awọn kosi ni idi "iṣofintoto lọna odi" Iba ọrọ yi ni Ariyọ pe n "fifi nkan han ilu lọna odi" nigbati o sọ pe "o ti gba lati ma fi nkan han ilu nibi lọna odi nipa eto iṣẹ ti Ijọba nṣe".

Lati da ikorira tabi ifinisinu silẹ larin Ọlọla Fadahunsi ati Ọgbẹni K. Y. M. Mackenizie, Ajẹlẹ wa, Ariyọ fẹnu ba ọrọ iwuri ti Ijẹṣa sọ nipa Ajẹlẹ na nipa iṣẹ rere rẹ a i ti iyawo rẹ ninu iwe ti wọn fi ki Gomina kabọ.

Niti emi, emi ko mọ ohun ti Ariyọ fẹ jẹ lere ni idi tembẹlẹkun to fẹ da silẹ larin awọn Ajẹlẹ ati awọn aṣoju wa ni igbimọ iṣofin. Niti Ọgbẹni Mackenzie, emi mọ pe ohun ti Ariyọ nfẹ ko le ṣe, nitoripe mo mọ pe Mackenzie gẹgẹbi Ajẹlẹ to fẹran iṣẹ, ko le ni iteriba fun Ajẹlẹ k'Ajẹlẹ to jẹ pe igbalẹfẹ ipari ọsẹ ni yio ma ba fọ sagbegbe "lati ṣe faji to npada si ibiti o fi se ibudo laiṣe nkankan fun awọn ipinlẹ na"

IWOSAN ỌFẸ

Lati bu ẹtẹ lu Ọlọla Fadahunsi nitoripe o sọ ni igbimọ iṣofin pe ko tọ ki wọn ma mu iwosan ọfẹ ti awọn ọmọde wa si ipinlẹ Ijẹṣa ati ipinlẹ miran ti ko de ni Ariyọ ṣe uran ni lati nipa sile-meji owo ilera ti ijọba Ijẹṣa nğba mowo ori lati fi ran ile iwosan kan na ti a ni lọwọ.

Ohun ti o fẹ ki awọn ọkawe rẹ gbagbọ nipe nitoripe Fadahunsi ti jẹ onijọ Metọdisti lo ṣe kọ kikọ ile iwosan ijọba nitoripe ko fẹ ki wọn ba ti ijọ Mẹtọdisti du iṣẹ pọ, pe dipo bẹ, o fẹ ki wọn ran ti Ijọ lọwọ.

Ohun to ndun mi ni wipe awọn ti nwa ebi si enia lẹsẹ bayi ki i ronu pe wọn ko le ma fi igbagbogbo tan aiye jẹ. Ti ko ba si ti bẹ o yẹ ki Ọgbẹni Ariyọ mọ pe gbogbo aiye ko i ti gbagbe pe Ijọba Ẹkun Iwọ Orun fi sinu iwe eto iṣẹ wọn nipa ilera pe awọn ipinlẹ ti ko ni ile iwosan rara ni awọn yio kọ ile iwosan si;

Njẹ kini ohun to le fa isọkusọ nigbana ti Ijẹṣa ba mu eyiti ọwọ wọn ba ni arauwa pinpin?

O dun ni pe awọn to npe ara wọn ni ọlọgbọn ko mọ pe iṣelu lọna ẹgbẹ-ko-ṣẹgbẹ
(Bẹrẹ ni oju iwe 5)

## AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

Afẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ N.NC mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

## LOCAL GOVERNMENT LAW

AND

## ITS APPLICATION IN

# IJESHA DIVISION

Councillor / Chief, ______________________

Here-under is a programme of events in connection with the opening of the Ijesha Divisional Council on April 18th. 1955.

Please read carefully and make it a point of duty to be punctual.

**Programme Of Events;- 16: 4·55**

1. Lecture at Obokungbusi hall 1: 30:p:m

   (I) Local Govt Law & its Application — by Mr. H. S. A Adedeji B. Com. (Lond)

   (II) The Standing Order — by Mr. Tunji Olowofoyeku BA. LL. B. Hons

   (III) The Duties of a Councillor — by Hon. J. O. Fadahunsi M.H.A.

2. Refreshment
3. Meeting of the Divisional Parliamentary Committee.
4. State-Service Sunday the 17th April. All councillors to Assemble at Pa. Ilesanmi's house at 9, a.m. Procession to Iloro Church Service starts at 10, a.m. Preacher Rev. D. O. Yoloye
5. Divisional Council meeting 18; 4: 55. 10 a-m.

All Divisional NCNC Councillors to assemble at Hon. J. O: Fadahunsi's house at 9. a.m. and from there go in a procession to the Council hall.

Hon. J. O. Fadahunsi M.H.A.
Leader NCNC

Olayinka Shiyanbola
Parliamentary Secretary

## AWỌN I'AN TI ỌSẸ YI

[Lati Ọwọ Ọgbẹni T. S. Falaiyei 97 Okesha St, Ilesa]

Inu mi iba dun bi ẹ le gba mi laye lati fi itan awọn ọrẹ meji yi si iwaju nyin.

Itan awọn Ọrẹ meji na lọ bayi:-

Awọn Ọkunrin, meji yi jọ nrin irin ajo lọ ninu igbo Nwọn si ṣe leri pe, ti ewu bade. Nwọn yio ran ara wọn lọwọ.

Bi nwọn ti rin si iwaju diẹ si, bẹni nwọn ri ẹranko buburu kan to nsare bọ lọdọ wọn. Ọkan ninu awọn Ọkunrin yi fo si ori igi. Nigbati Ọkunrin keji ripe, on ko le a'ọ mọ, ati pe ẹranko na ti sunmọ on, o ṣubu lulẹ gbaragada, o si ṣe bi ẹniti o ti ku.

Ẹranko yi ki jẹ oku enia. Nigbati o de ọdọ Ọkunrin yi, o gborun ara rẹ wo, o ro pe o ti ku ni, o si ba tirẹ lọ.

Nigbati ọkunrin ti o gun igi yi sọkalẹ, o bere lọwọ Ọrẹ rẹ ohun ti ẹranko na wi fun. Nitoripe on ri ti o fi ẹnu si ibi eti rẹ, ọrẹ rẹ ni „A„ o ni ki nsọfun ọ pe ojo ni ọ. O si wipe ki nma tun gba ọrẹ ti o ba ṣe ileri pe, on yio duro ti on ni asiko ewu ti o si nsa lọ bi irufẹ tirẹ gbọ mọ.

Itan yi kọ wa wipe. Ki a ma sọfun ara wa bi ewu de

Ọkọ Ọba koni sa Olotu iwe Irawọ Obokun lẹsẹ o

AHUN ATI WURA RẸ

Itan kekere keji ti mo fẹ sọ ni ọsẹ yi ni itan Ahun ati wura rẹ. Itan na lọ bayi

Ọkunrin olowo kan wa ti o ta gbogbo nkan rẹ o si lọ fi ra wura o wa ri i mọlẹ.

O ma nlọ bẹ wura na wo ni ojojumọ. Awọn ole wa bẹrẹ si iṣọ

Nigbati nwọn mọ ibi ti o fi si. Nwọn lọ hu, nwọn gbe lọ

N gba baba yi tun lọ wo wura rẹ ti ko ri nibẹ mọ o dun pupọ o si bẹrẹ si sọkun

Ọkunrin kan ti o jẹ aladugbo rẹ sọfun pe, Ọrẹ mi kini ṣe ti iwọ fi nsọkun? nigbati o wa nibẹ ṣe o ko lo wu ọ lati ma ri i lasan ni? Emi rope. okuta yio wulo pupọ fun ọ, nigbati o ba ri imọlẹ ti o si mbẹ wo loju-mọ

Itan yi ko wa wipe bi a ba ni nkan lati fi pamọ, ki a jẹki ẹnikẹni mọ ibiti ao fi pamọ si o

# E ma ka Irawọ Obokun, ki ẹ si ma p'olowo oja yin sinu re nitoripe tiyin ni.



KAN E.O M I EKUNDARE

On jẹ ọkan ninu Ọmọ NCNC ti Iṣeto Ijọba yio bọ si lọwọ laipẹ Akọwe ẹgbẹ na ti ṣe alaye nipa ... pe ijọba ti fi iwe sọwọ pe lẹhin ọdun yi owo omi yio di ṣile marundogun.

# E ka Irawo Obokun

## ẸGBẸ ỌLỌPẸ ATI OMI ẸRỌ

Bẹrẹ Lati oju iwe 1

gbati a gbọ pe Ọlọla E. A. Babalọla, ẹniti o jẹ oluṣeto fun eto iṣiṣẹ Ẹkun Iwọ Orun nbọ, a ni igbẹkẹle wipe on yio ṣe alaye lori iye ti ijọba wọn pa laṣẹ pe wọn fẹ ki awọn asanwori Ilẹsa ma san fun owo omi ẹrọ lẹhin ọdun yi.

Ṣugbọn ohun ti o ya wa lẹnu nipe o dabi ẹnipe awọn eleto Ijọba Ẹkun Iwọ Orun fẹ ti ẹru ti wọn ti di kalẹ mọ ẹlomiran lori.

OMI OLOWO KEKERE

Ninu ọrọ Ọlọla na, o ki Ijẹṣa ku orire pe omi olowo kekere ni omi ẹrọ wọn. O ni oke lo ti nsan walẹ nitorina ko ni inawo bi ti ibomiran O fi ti Oṣogbo ṣe akawe pe o ṣe e ṣe ki owo omi ti asanwori kọkan yio ma ṣan to poun mẹta ẹnikọkan, o ni ṣugbọn ti Ilẹṣa ko le to bẹ nitoripe oke lo ti nṣan walẹ.

Ọlọla na sọrọ rẹ siwaju si wipe Ijẹṣa yio san owo omi; o ni owo na ko ni pọ, o ni ijọba Ilẹṣa ni yio bu owo na.

Pipari ti Ọlọla na pari ọrọ rẹ tan ni awọn ẹgbẹ Ọlọpẹ ti bẹrẹ kundekunde pe Minista tio ni aṣẹ eto omi ti sọ pe owo omi ko gbọdọ pọ. Wọn ni o ti sọpe Ijẹṣa y'orire nitoripe oke ni omi wọn ti ṣan walẹ nitorina owo kekere ni wọn yio ma san fun.

Wọn ma nso pe ti o ba ri bẹ awọn ko ri idi ti owo omi fi ni lati ju sisi (6d) tabi ṣile kan (1s) lọ. fun asanwo'ri kọkan.

AKIYESI PATAKI

Pataki ohun ti a fẹ ki ẹnyin ọkaare wa ṣe akiyesi nipe Ọlọla E. A. Babalọla ati opọlọpọ awọn ẹmọ ẹlọpẹ wọnyi, papa awọn to jẹ Kansẹlọ ninu wọn mọ pe iwe aṣẹ kan ti de lati ọdọ Ijọba wọn ni Ibadan si ijọba Ibilẹ Ijẹṣa nipa iye owo ti wọn fẹ ki asanwori kọkan ma san fun owo omi.

Ọrọ iwe aṣẹ na ṣe pataki ju eyiti Ọlọla na ni lati tọ fo, ṣugbọn titọ ti o tọ fo, ati iru kundekunde ti awọn ọm Ọlọpẹ ti nṣe lati igbati o ti lọ, fi nyeni pe afẹnuba ọrọ na nidi.

Wọn mọ wipe lẹhin ti ẹmi ijọba ibilẹ Ijẹṣa to wa lode oni ba dopin, agbara iṣejọba yio bọ sọwọ ẹgbẹ NCNC. Wọn ti fi sinu iwe aṣẹ na pe ijọba wọn gba ki asanwori Ilẹṣa san ṣile marun marun (5s) owo mi ni ọdun yi; ṣugbọn lẹhin ti ọdun yi, iwe aṣẹ ti wọn fi sọwọ sọ wipe "owo omi ti ọjọ iwaju yio fẹrẹ to ṣile marundogun (15s.)

Gẹgẹ bi ero ọkan gbogbo awọn to mọ otitọ ọrọ yi ohun ti awọn ọlọpẹ fẹ ṣe nipe lẹhin ọdun yi, nigbati agbara iṣejọba ba ti wa lọwọ Alakukọ ni ẹkunrẹrẹ, ti owo omi ba di ṣile marundogun gẹgẹbi aṣẹ wọn, ni awọn agbodegba wọn yio ma ke kiri pe ijọba ẹgbẹ Alakukọ ti gbe ẹru wiwuwo le Ijẹṣa lori.

IWE NA NI YI O

Fun anfani gbogbo awọn to fẹran otitọ, eyi ni iwe aṣẹ na ni ede Yoruba:-

"Lori ohun ti ijọba Ibilẹ ti Ipinlẹ Ijẹṣa fẹ, Ọlọla julọ, Gomina ti gba ṣile marun gẹgẹbi owo ti awọn ọmọkunrin lati ọmọ ọlọdun merindinlogun soke yio san gẹgẹbi owo omi. Iyẹn ni awọn to ngbe igboro Ilẹṣa.

"2. Isanwo na jẹ eyiti o lorukọ a si gbe gbigba rẹ kalẹ fun ayipo ọdun iṣiṣẹ kan pere. Lati ọjọ kin oṣu April 1955 nigbati iye owo ti a o fi ṣe omi na ati eyi ti a fi ngbe lọwọ yio jẹ mimọ, ao fọ elewo diẹ, owo omi ti ọjọ iwaju yio fẹrẹ to ṣile marundogun (15s).

"3. Aṣedelẹ atunṣe sisan owo na ni a o tẹ jade fun gbogbo enia lati rika gere lẹhin igbati a ba ti ṣe iṣiro iṣẹ omi na pẹlu igbelọwọ rẹ ti o ba si ti jẹ mimọ".

Nọmba iwe aṣẹ na jẹ 198/32. Wọn kọ ni 7/3/55.

Bayi ni iwe aṣẹ na ka lede Gẹsi.

"LETTER FROM REGIONAL GOVERNMENT 198/32"

"On the application of the Ijesha Divisional Native Administration, His Excellency the Governor approved the collection of a 5s water rate to be paid during 1954-55 by all male of 16 years and over, resident in Ilesha town.

"2. This rate is a nominal one

Bẹrẹ ni oju iwe 6



Western Region Local Government No. 1 of 1953 47

Assented to in Her Majesty's name this 25 day of February, 1953

Lieutenant-Governor, Western Region

PUBLIC SEAL

No. 1 1953

Western Region of Nigeria

IN THE SECOND YEAR OF THE REIGN OF

HER MAJESTY QUEEN ELIZABETH II

HUGO FRANK MARSHALL, C.M.G.

Lieutenant-Governor, Western Region

A LAW TO MAKE PROVISION FOR LOCAL GOVERNMENT IN THE WESTERN REGION AND FOR PURPOSES CONNECTED THEREWITH.

[26th February, 1953] Date of commencement.

BE IT ENACTED by the Legislature of the Western Region of Nigeria as follows:— Enactment.

PART 1.—PRELIMINARY

1. This Law may be cited as the Western Region Local Government Law, 1952. Short title.

2. Definitions— Definitions.

"chairman" means the chairman of a council elected under section 23 of this Law, and includes any person presiding at a meeting of a council in the absence of the chairman by virtue of the provisions of section 40 of this Law.

"chief" means any person recognised as a chief by the Lieutenant-Governor.

IWE ẸRI FUN IGBEKALẸ IJỌBA TITUN

Eyi yi ni aworan ti iwe ẹri ti wọn fọwọ si lorukọ Ọba Ilu Gẹsi fun eto igbekalẹ Ijọba titun. Eto Ijọba na ti bẹbẹ ni ọpọlọpọ Ipinlẹ. Wọn si ti nsari iṣibo ti ilẹ Ijẹṣa. Wọn yio ṣe ipadọ kini ni ọjọ [illegible] ọsẹ yi.



AWỌN AṢOJU NI IGBIMO IṢOFIN

Ogunlogo awọn to nṣe aṣoju ni Igbimọ Iṣofin lo jẹ Olukọ gẹgẹbi ọrọ Ọgbẹni Akindele Ojo. O ni nitoribẹ on gba pe eniti o jẹ Oluṣeto fun eto ẹkọ ko ni ka iwe ebẹ ti Ọgbeni Ariyọ kọ si.

# ASARO LORI OHUNKOHUN

## ARIYỌ ATI AWỌN AṢOJU IJẸṢA

Bẹrẹ Lati oju iwe 2

ni ala. Ti o ba jẹ pe wọn mọ ni, emi ko ri idi ti Ariyọ fi fi gbogbo ẹnu nariwo iba owo kekere ti ijọba fun ile iwosan kansoso ti o wa ni Ilẹ Ijẹṣa. Nitori pe o jẹ mimọ si ọpọlọpọ enia pe wọn ti fi owo to ga ju bẹ lọ fun ile iwosan miran ni ipinle miran papa ni ipinlẹ ti awọn ọlọpẹ ti lẹṣẹ nlẹ.

### OWO OṢU NI IGBIMO

Ọgbẹni Ade Ariyọ fi ara rẹ han gan a nigbati o bẹrẹ kikun nipa owo oṣu ti ijọba nsan fun awọn aṣoju Ijẹṣa ni igbimọ iṣofin bi ẹnipe awọn aṣoju lati Ipinlẹ miran ki i gbowo oṣu.

Bi o ti nkuro lori eyi ni lo bẹrẹ si i sọrọ lodi si ara rẹ nigbati o sọ pe wọn ntako ijọba to nfun wọn lowo oṣu bi ẹnipe Ọlọla S L. Akintọla, ẹniti o jẹ oluwa titun si Ariyọ ko ntako ijọba akopọ bai-jiria to nfun on na lowo oṣu ju eyi ti Ijọba Ẹkun Iwọ Orun nfun awọn aṣoju ti wọn.

Ifẹ inu rẹ ni wipe ki Ogbẹni J. A. Akinyẹmi wọle idibo ti ijọba akopọ, ṣugbọn ko fi ye wa boya Ọgbẹni na ko ni gbowo oṣu to ba wọle Ariyọ kan nji adu lati gbe Ọgbẹni Akinyẹmi de ibiti ko le gbe de lasiko idibo na.

Nitori Ọlọrun, mo nbẹ Ariyọ ki o fi Akinyẹmi silẹ nitoripe Ogbẹni na, ẹniti gbo-gbo Ijẹṣa lowọ ati ọ a fun, ti gba awọ ẹ rẹ gẹgẹbi ẹniti o tayo ti ko je.

Ṣugbọn mo ba Ariyọ kẹ-dun nitori ipolunrere ẹkun rẹ nitori alraye gba ohun ti iba gba ti ọmọ ọlọpẹ ba bo ri ni Ilesa nigba idibo na.

### RELUWE AKINIOLA

Fiti emi aṣoto sọrọ nipa ọna Reluwe ti Ọlọla Akin-tọla se wa si Ilesa jẹ idi pataki ti Ariyọ fi ni lati jẹ ẹni idalebi lokan gbogbo awọn Ijẹṣa gidi nibikibi ti wọn le wa.

Igbati Ọlọla Fadahunsi nsọrọ lori ohun to ndun Ijẹṣa pe Ijọba ko fun wọn ni iwosan ọfẹ ti nwọn sanwo fun, Ariyọ so pe tẹlẹgbẹ iṣelu lo nse, ṣugbọn igbati Ọlọla Akintọla joko si igbimọ iṣofin, to si nto iṣin ọna Re-luwe lọ si Ilesa, Ariyọ fẹ ki a gba gbọ pe on ko ṣe tẹlẹ gbẹ iselu.

Emi mọ pe yiyan ti a yan Ọlọ'a C.O Kọmọlafẹ sigbimọ ijọba Akopọ jẹ irora nla lara Ariyọ ati awọn bi tirẹ, irora

Bẹrẹ ni oju iwe 8

## IDOWU OGUNDIPẸ BI ỌMỌKUNRIN KAN

(Lati ọwọ J. O. Awosan

Ni ojo iimọ tiṣe ọjọkẹdọ gbọu [25.3.55] osu to kọja ni. Pẹlade tiṣe Iyawo Idowu Ogundipẹ bi ọmọkunrin lantilanti kan ni adugbo wọn ni Ogburu.

Bi awọn ọrẹ Idowu tigbọ irohin ayọ yi ni wọn lọ si ile rẹ lati lọ ki ati lati yọ fun nitori ore ti Ọlọruu ṣe fun on ati Iyawo rẹ

Lẹṣẹkanna ni baba ọmọ titun ba bẹrẹsi fi ọti ati ẹmu se awọn enia na ni ale-jo.

Idowu Ogundipẹ jẹ aburo ologbe Jesua Ogundipọ ni adugbo Ogburu. On si nṣe ṣẹ Chaterer ni ibusọ Motọ ni Ileṣa.

Akọle Olotu a ki Ọgbẹni Idowu Ogundipẹ ati Iyawo rẹ ku orire ti ọmọ titun ti Ọlọrun fun wọn. Ọlọrun yio ṣe ni ọmọ alalubarika ni igbesi aiye rẹ. Ọba Edu-mare jọwọ fi rere bayi kari gbogbgo wa o.


# AKIYESI PATAKI

## IWE ALAGBAFO ASO

A ṢE IWE YI FUN ANFANI AWỌN ALAGBAFỌ ATI AWỌN TI A NFO ASỌ FUN. NIPA IWE YI AṢỌ KO SỌNU MỌ.

KARA ARIYANJIYAN KO SI MỌ NIPA AṢỌ.

TETE RA TIRẸ KI O TO TAN. IBA DIẸ NI A ṢE.

O RI IWE YI RA NI OFFICE:- IJESHA PRESS LTD.




ỌGBẸNI J A AKINYẸMI

Ọgbẹni Akindele Ojo nbẹ Ariyọ pe ki o fi Ọgbẹni wa yi silẹ nitoripe ẹ ti fi ẹmi otito gba aiwọle rẹ. O ni ki i ṣe ohun to dara pe ki Ariyọ ma gbiyanju lati gbo de ibiti o ti yọ ki o to gbeda lasiko idibo.

## OMI TI KO DE'NI L'ẸṢẸ

(Bẹrẹ Lati Oju Iwe 6)

ti a ba ma ṣọ otitọ pe kia mu ti Ẹgan kuro, ti aba fi oju inu wo arin awọn ẹgbẹ wọnyi ah! nibẹ ni mo ti mọ daju gẹgẹbi ọrọ Ọlọrun ti o sọ ninu iwe mimọ rẹ [Bibeli] pe „Enia koni ibi ikọṣẹ meji bikoṣe nipa sẹ awọn obirin

Obirin toto, awọn lo nri ole ti tọka rẹ si ẹlẹru, awon ni wọn tun pe oloko pe ki o wa mu ole.

Orin oṣere wa, Ọgbẹni C. A B yio tun bọ fi ọrọ na han wa pe ko si ohun ti obirin ko le da silẹ.

Ninu awọn ti o nru enia loju diẹ ni iwa biba ẹgbẹ jẹ yi. Mo ti ri diẹ ninu wọn nipa isẹ obirin. Ni adugbo Oke iro' ninu ẹgbẹ kan bayi, ẹnyin ko mọ bi ọrọ na ti le to.?

Ẹni ti a fi ṣe Bale ile ti o njẹ ọgbọn okele ah! Aiye ga ju Ọrun lọ.

Ẹniti a pe ni Ole ti o ngbe ọmọ Ewurẹ ṣere. O ṣẹlẹpe awọn diẹ ninu ẹgbẹ ti wọn jẹ obirin yi fi ọrọ itugbẹ wọn han, wọn si nta biọbiọ, wọn njakun lati tu itẹ ẹiyẹ, sugbọn wọn ko ṣe iranti ile ti a kọ si eri apata. Ni idi eyi, wọn pinu, wọn jẹ Oloye larin ẹgbẹ yi wọn si ṣe ileri lati sọ ẹgbẹ na kalẹ gẹgẹbi orukọ ti wọn fun ara wọn.

Ṣugbọn a ki su igbẹ riro si tosi ile. Gbogbo awọn ẹgbẹ na kunde de adugbo ati ile awọn mọdaru yi, pe "Kọlọmọ tẹ ọmọ rẹ bọṣọ o" ki dede ja ọmọ a'e lo nfa ati pe wọn fi ye wọn diẹ ninu itan tabi ọrọ were ọna Ijẹbu ti o njẹ ẹsinṣin.

Nisisiyi ẹnyin agba ninu ẹgbẹ ati ẹnyin ajunilọ, ori kan ko le to ti enia mẹw-ki alaja so aja rẹ mọ oruso nitori wọn nfẹ lati wa ma tọka si iyọnu o. Nitori ki dede ọmọ ale lo nfa o, bẹni ninu awọn diẹ na wọn ko ṣe iranti pe wọn ra otitẹ Ijọba, wọn si ṣe ileri lati mase ma a lodi si eto ẹgbẹ.

Pataki ọrọ nipe aṣe ifilọ yi fun ajunilọ ati awọn aṣaju ninu ẹgbẹ fun atuṣe ọrọ na, lẹhin eyi a o ma reti eto yin, nitori afọrọsun ki jẹbi o, nitori emi nfẹ, a ko si fẹ ki o jẹ ailera fun ara; nitori OMI TI KO DE NI LẸṢẸ KI TU NI LAṢỌ O!

Mo dupẹ pupọ lọwọ awọn ọkawe wa Irawọ Obokun ati Olotu Irawọ Opokun ko ni subu o, amin

## IDAHUN SI IBERE ỌGBENI T. S FALAYE

[Lati ọwọ Gab Kayọde Ige Alowolodu AT 6A Ijọka St. Ilesa]

Inu mi yio dun bi Olotu ba lẹ gba mi laye lati fesi diẹ si ibere ti Ọgbẹni T. S Falẹyẹ to ngbe B 97 Okeṣa, ti o jade ni 28-3 65. Ibere na niyi.- Owo ati Ọmọ ewo lagba?

Ibere na dara pupọ ṣ gbọn pataki ni awọn mejeji. Suru ni agba wọn. Lotọ awọn agba ma npa lowe wipe olowo ko ri ọmọ ra. Ṣugbọn ti enia ba nfẹ iyawo lode ohun ti o ma bere ni owo idahun. Njẹ ti enia ko ba lowo njẹ o le fun Obirin na ni owo ti o to £10-10? Njẹ ti o ba sọ fun obirin na pe on ko ni ju £2-10 ẹ ro pe irufẹ Ọkunrin bẹ le ti bẹ ri Iyawo fẹ, depo pe ki o ri ọmọ bi?

Nitorina Owo ju ọmọ lọ pupọ o. Ṣe ẹnyin na se akiyesi awọn agba npa lowe wipe owo lẹgbọn ọmọ laburo. Ṣe ẹ ri wipe Iwe Mimọ na tun sọ wipe owo ni gbongbo ẹṣẹ. on si ni idahun ohun gbogbo. Nitorina ohun ko hun ga ba fẹ ṣe la iye yi ti ko a ti si owo nibẹ ko le ṣe ṣe o Owo lati kọile, owo lati nbimọ owo lati nranṣọ owo owo owo ape kanu ko.

Jọwọ Olotu gbami laye kekere lati ṣe Ibere mi kekere yi lọwọ awọn ọkawe Irawọ Obokun. Awọn agba lo si npa lowe wipe ẹnito ba bere ọrọ lo fẹ idi rẹ ni gbi gbọ.

Ẹ jọwọ Olowo lati Ologun ewo lagba· Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gbami Ọkọ Ọba ko ni sa yin lẹsẹ. Amin o digba diẹ na.

**Bring your Printing Jobs to:-**

**Ijesha Press Ltd.**
**Okesha Street,**
**ILESHA.**



ỌLỌLA S.O AWOKỌYA

On jẹ ọkan ninu awọn ti Ọgbẹni Ade. Ariyọ kọ iwe ẹbẹ si nkan wọn Oluseto ile iwe to di Kansẹlọ, Ọgbẹni Akindele Ojo nsọ pe on ko ka iwe ẹbẹ na si nitoripe Lati Olukọ ni on na ti di Minista.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. „ | „ „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ . |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ . . |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## ARIYỌ ATI AWỌN AṢOJU IJẸṢA

(Bẹrẹ lati oju iwe 5)

ala na ko si le rọ wọn lanai.

Mo gbọ, mo si mọ dada wipe Ariyọ ti kọ iwe ẹbẹ kan gigun nipa Olu Kọmọlafẹ ati ọpọlọpọ awọn Olukọ Ileṣa Grammar School ranṣẹ si Oluṣeto ikẹkọ, Ajẹlẹ ati igbimọ alaṣẹ ile ẹkọ giga na.

Ẹkun ti oniwe ẹbẹ na nsun nipe ọpọlọpọ awọn Olukọ ile ẹkọ giga na ati ti ile ẹkọ miran, lo ti di Kanselọ, ipo ti Ariyọ fẹ lati de ṣugbọn ti Ijẹṣa ko yan si. O sọ niti Olu Kọmọlafẹ pe igbimọ isofin ti gba eyiti o ju ninu asiko rẹ.

Ni temi, mo mọ pe Oluṣeto ikẹkọ ko ni ka ọrọ rẹ si nkankan, nitoripe Olukọ ni on papa ki wọn to yan si igbimọ. Ajẹlẹ ati igbimọ alaṣẹ ile ẹkọ giga na ko ni ka ọrọ rẹ si nitoripe ẹlabojuto ile ẹkọ giga na papa wa ninu awọn to wọle Kanselọ si ọkan ninu awọn igbimọ agbegbe.

Ohun to yami lẹnu ti emi kosi mọ idi rẹ nipe emi ko mọ kini idi ti awọn Jeremia ẹlẹkun fi nwa ọwọ mọri nitori ohun to ti di aṣa nibikibi.

Ki emi to pari iwe yi, yio wu mi lati fi ọkan awọn obi ọmọ ile ẹkọ balẹ pe kosi idi ti wọn fi n lati gba pe ọrẹ na le pa ẹkọ ọmọ wọn lara.

Mo fẹ lati fi da wọn loju pe ẹgbẹ Alakoko, gẹgẹbi ẹgbẹ iselu to feran itẹsiwaju ninu ohun gbogbo, to si mọ pataki ẹkọ, yio se eto lati ripe sise Kanselo ọpọlọpọ olukọ ko pa ẹko ọmọ wọn lara.

[Bẹrẹ lose to nbọ.]

## A K I Y E S I

A fi eyi kede fun gbogbo awọn aṣoju wa ti mba wa ta iwe irohin yi pe, aṣoju k'aṣoju ti ko ba san owo iwe tire ki o to di ipari Ọsẹ kini ti yio tẹle Oṣu, a o da iwe rẹ duro lai si ifilọ tabi ifisun.

Nipa aṣẹ
A abojuto

## AKIYESI PATAKI

FUN GBOGBO ẸNITO BA FẸ RA AWỌN NKAN WỌNYI.-

Iwe ogun I ọye Aiye 3/- Iroka orire Ajẹbidan Irawọ wiwo Is sile kan. Bere iwe itaja wa, kọwe si P.O. Box 73 tabi ko wa si O. 157 Ikoti Street Ilesha

Dr. Prof. J. A. Longẹ.



ỌGBẸNI ATI ARABIRIN J. A ADEDAPỌ

Ọgbẹni J A Adedapọ jẹ ọkan ninu awọn Aṣaju Ẹgbẹ Ọdọ ti wọn npe ni Ever-Ready. Ọgbẹni F Adeleye nda laba ninu iwe ọsẹ yi pe o yẹ ki Ijọba ma fotin ran Ẹgbẹ ọdọ lọwọ.

## E KA NIPA IJOBA YIN

Laipẹ yi, ilẹ Ijẹṣa yio di ọkan ninu awọn ipinlẹ ti o ni ijọba alajumọ-ṣepọ nipa nini igbimọ iṣejọba mejilelogun.

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olukuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orisirisi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa ba fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe.

Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.
A fẹ aṣoju si ni Ileṣa.
A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.
A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.
A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Eto bi olukuluku ṣe le ma ra tabi ma ta iwe wa wa ni isalẹ iwe yi.

| | | |
|---|---|---|
| Deposit | 10 to 50 Copies -- | 10/- |
| | 50 to 100 ,, -- | 20/ |
| | 100 to 200 ,, -- | 4 /- |
| Commission:- | 10 to 100 copies | 20o/o (4/- in £1) |
| | 100 to 1000 ,, | 25o/o (5/- in £1) |
| From 1000 upwards | | Special arrangement. |

All payments should be made during 1st week in the following month, latest 2nd week after which supply would be cut off without notice.

Deposit could be withdrawn after a month's notice should in case the Agent does not owe any arrears if he or she wishes to discontinue the Agency.

## FUN TITA

Motọ Ayọkẹlẹ (Car) kan wa fun tita. Orukọ motọ ayọkẹlẹ Ina ni HUMBER HAWK.

Gbogbo ẹya ara rẹ lo wa dada, a ko lo ni ilokulo, o si wa ni abẹ itọju nigba gbogbo.

Enikẹni ti o ba ni ifẹ lati yẹwo ki o ri Ọgbẹni J.A. AKINYẸMI ni ọgba Grammar School Ilesha ni asiko kasiko

### IGBIMỌ IYANILOWO

Eyi ni lati fi ṣe ikede pe a fẹ ki awọn agbẹ to ti kọwe fun ẹrọ ati ogun ti wọn fi npa korikori lara Koko wa sibi iṣẹ ijọba ni ọjọ kẹfa oṣu yi lati agogo mẹwa soke.

A si bẹ olukuluku lati mu oluduro rẹ dani wa

AKỌWE

## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

AKỌWE

## AKIYESI PATAKI

Ki ẹnikẹni ti o ba fẹ kowe sinu iwe Irawọ Obokun ma kọ orukọ ti on papa nje pelu adugbo rẹ. Toripe ọpọ iwe ni anri gba laisi orukọ. Eyiti ko basi ni orukọ ako ni tẹ jade.

ALABOJUTO

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B110 & B149 Okeśla Street, Ilesha 11 - 4 - 55